



# Irohin Yoruba

A Newspaper of the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd

VOL. XII NO. 597. NOVEMBER 19—NOVEMBER 25, 1956. KOBO MEJI (2D.)



VOMICURE

FUN ARA-YIYA NI GBOGBO ... VOMICURE.

EJIWUNMI MEDICINE STORES

... Street, Lagos.


# EGBE AFENIFERE SEGUN EGBE N.P.C. NI ILORIN ATI L'OFFA



MALLAM IBRAHIM LARO

**NINU idibo gbogbogboo iwọle Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Ariwa. Ẹgbẹ Ilọrin Talaka Parapọ dapọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ni o ṣẹgun ni Ilọrin ati l'Ọffa. Ninu adi-gbẹhin ibo ti nwọn di ni Iha Ariwa Ilu Ilọrin, Olori Ẹgbẹ Ilọrin, Talaka Parapọ dapọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre, Alhaji Maito ni o ṣẹgun Mallam Sulu Gambari ti awọn Ẹgbẹ N.P.C. yan sode lati dibo fun. Ibo ti Alhaji gba jẹ mẹtalelogoji (43 votes), ti Mallam Sulu Gambari jẹ mọkanlelogun (21 votes).**

Ni Iha Ariwa Ilorin Ogbeni J. G. Ekunrin ti awọn Ẹgbẹ Igbomina Parapọ dapọ mọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni o ṣẹgun Ogbeni Daniel Malọmọ Babajami ti awọn Ẹgbẹ NPC yan sode lati dibo fun. Ogbeni J. G. Ekunrin, aṣoju Ẹgbẹ Igbomina Parapọ mọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre gba ibo ọgbọn 30 (votes) ninu ibo adigbẹhin. Ogbeni Daniel Malọmọ Babajami ti iṣe aṣoju Ẹgbẹ NPC gba ibo mọkanlelogun (21 votes)

IBRAHIM WOLE

Ayorisi idibo l'ọna taara ti nwọn ko ṣe ninu ilu Ilọrin paapa ni ọjọ Ọjọbọ ti o koja lọ yi, Talaka Parapọ dapọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ni o ṣẹgun NPC. Mallam Ibrahim Laro ti awọn Ẹgbẹ Ilorin Talaka Parapọ dapọmọ Ẹgbẹ Afẹfere yan sode ni o ṣẹgun Alhaji Sa'adu Alanamu aṣoju Ẹgbẹ NPC. Ibo ti Mallam Ibrahim Laro gba jẹ 3,710 ti Sa'adu Alanamu jẹ 3,226 eyiti Ibrahim Laro fi ṣẹgun Alanamu jẹ 490. ni Offa ati agbegbe rẹ ti 1,776 pere. Eyiti abaniləje lati ṣi i te, a si bẹ Ogbeni wọju si ni ilu na.

IDIBO OFFA

Ayorisi akọkọ dibo ti ọna taara ni Ipinlẹ Ariwa ti ilu Offa ni o kọkọ jade; Ogbeni

*Wo oju ewe kejila*



JOSIAH SUNDAY OLAWOYIN
(Akowe Agba Egbe Afenifere Offa)

## Igbimọ Amuludagba Iwc-Orun lo bẹ Oke-Okun wo

IBADAN.

NI ọjọ Isegun ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi ni awọn mẹfa ninu Igbimọ Amuludagba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria, Ogbeni A. O. Rewane Obakeji Alaga Igbimọ na, Oloye A. M. Adebule Oloye J. O. Kasnimawo, Ogbeni S. O. Shonibare, Ogbeni S. Y. Eke ati Ogbeni L. Omole lọ si Accra Oke-Okun (Gold Coast) lọ ṣe ibẹwo bi ohun ọgbin ati iṣe sise won ti ṣe ngni ilosiwaju si ni ilu na.

Lẹnulọloyi ni awọn enia pataki pataki inu Igbimọ Amuludagba ti Oke -Okun (Gold Coast) wa ṣe ibẹwo ohun ọgbin ati iṣẹ sise ti Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria nihin bi o ti ṣe ngberu siwaju a ti siwaju si. Lori ajoso won pẹlu Igbimọ Amuludagba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria nipa ohun ọgbin ati iṣẹ-sise ti Oke-okun ni awọn Igbimọ Amuludagba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria na ba fi lọ fun ìrafẹ ibẹwo bẹ e ti awọn na wa ṣe ni Ipinlẹ tiwọn na.

## Igbimọ Iwadi Banki pari ipade

IGBIMỌ Iwadi Ọlọla Foster Sutton Olori Adajọ Apapọ Ijọba Naijiria lori ẹsun aiṣedeede African Continental Bank ati Dokita Azikiwe ti iṣe Olori Ẹgbẹ NCNC ati Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun ti o ti bere lati ọjọ kẹtadinlogbọn oṣu kejọ ọdun yi pari ni ipari ọsẹ ti o koja yi.

Lẹhin ti nwọn ti gbọ ọrọ lati ẹnu awọn ẹlẹri tan ni awọn agbẹjọro awọn ti ọran na kan bere si ṣe alaye wọn fun Alaga Igbimọ na lori ọrọ awọn ẹlẹri kọọkan gẹgẹ bi ọrọ ikadi ọran.

Ogbeni E. I. Mallalieu, Q.C. ti iṣe agbẹjọro African Continental Bank ni o kọ sọrọ, o ni ti o tilẹjẹpe aiṣedeede wa ninu eto iṣẹ Banki na lọtun ati losi, sibẹ on ko ri i pe nkan danindanin kan nlyẹn.

Ogbeni Udo Udoma ti iṣe agbẹjọro awọn Ẹgbẹ Alatako Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun o ni ẹri ti o fi oju han ninu ọran yi, o ni iwa ti Dokita Azikiwe hu nipa ajumọṣe rẹ pẹlu iṣẹ African Continental Bank yi o ko ifasẹhin pupọ ba Naijiria gẹgẹbi orilẹ-ede ti o ṣẹṣẹ ndide ati pe ero Azikiwe ni pe o nfẹ di oṣelu ti o lowo julọ ki apa rẹ ki o le ka Ipinlẹ Ila-Orun.

Ogbeni M. O. Balonwu, Agbẹjọro ti o wa fun awọn Minista Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun ninu ọran iwadi Banki yi ni gbogbo ọna ti awọn Minista Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun gba nipa bi owo Ijọba ti ṣe de African Contal Bank jẹ ohun ti nwọn ṣe lati fi iwa otito inu wọn han ni.

Lẹhin eyi ni Ogbeni C. Shawcross Q.C. ti iṣe Agbẹjọro Ogbeni E. O. Eyo eniti o mu ẹsun Dokita Azikiwe ati Banki na wa siwaju Ijọba ki ọran na to di titupale, sọ wipe on ko ni alaye

*Wo oju ewe kejila*



# Igbimọ Iwadi Continental Banki pari ipade

*Lati oju ewe kini*

lati tun se mọ, nitori nkan pataki ti Ọgbẹni Ẹyọ ti o gba ọa ni lọja fẹ ki o ṣe ni Iwadi Banki, ọran na si ti se, awọn ọri ti o si wa niwaju awọn Igbimọ Oluwadi Banki na si tu gbogbo asiri ti Ọgbẹni Ẹyọ nfẹ ki o jade sita.

Lẹhin igbana ni ọrọ kan Ọgbẹni Frank Sosokire Q.C. eniti ise Agbẹjọro awọn agbejoro Dokita Azikiwe, o ni ọran ti o wa nibe yi ẹrẹg-bi alaye ti on, o ni ki ise nipa aisedeede iwa Dokita Azikiwe ninu ọran iselu tabi iwa rẹ ni ona miran sa a. O ni nipa ti ọran Banki yi ti o je pataki ọran Iwadi na ni on ri wipe Dokita Azikiwe ko ni ikọse nibe.

Nigbadu ni o wa kan "Egun nla ti gbehin igbale" Ọlọla H. J. M. Mackenna Q.C. ti ise Agbẹjoro awọn Igbimọ Oluwadi ọran na, ni on ti on ri ti on o se alaye le lori gegebi awọn ọri ti nwọn je niwaju Igbimọ Oluwadi na ni:

Pe Azikiwe ni o so fun Ọgbẹni Ẹyọ pe ki o f imọran at i ko owo Ijọba £30,000 si Banki na si iwaju Ijọba.

Pe Azikiwe lo ogbon aro-daroda lati fi mu ki Adele-Gomina Ipinle Ila-Orun gba lati fi ko owo Ijọbo si Banki na.

Pe Azikiwe, Blankson ati Ojike ti pinnu eto bi Corporation ti se fi owo sinu Banki na.

Pe gbogbo bi eto adehun a ti fi owo na si Banki na ni Azikiwe mọ lati oke dele.

Pe Azikiwe ni o ko Ojike pe ki o ma ba awọn Igbimọ ọ o ki nwọn to fi owo na sibe.

Pe awọn Igbimọ Finance Corporation ko fi ase si iwe adehun ti o wa larin on ati Banki na.

Pe Dokita Mbanugo ko ni ase lati se iwe-adehun fun Banki na bi asoju.

Pe ati̇nse ti nwọn se lori eto ise Banki na si fun Azikiwe laye lati pada di alase Banki na nigbakigba.

Pe Azikiwe si ti mọ ki nwọn to se eto ise Banki na bẹẹ ati pe o si ti tun mọ lẹhin ti nwọn tun se e tan.

Pe Idi Mbanugo ati Blankson fi lọ si ilu Oyinbo fun ni pe nwọn a ti lẹkun Banki na ni ọjọ kejilelogun osu May bi ko ba ni iwe ase Ijọba.

Pe Azikiwe, Ojike, Blankson ati Okoye ko sọ otito rara ninu ọrọ wọn niwaju awọn Igbimọ Oluwadi na.

Gbogbo ọrọ wonyi ni Ọgbẹni MacKenna se alaye le lori lọkọọkan lesẹẹse ati ni kikun ni ipari gbogbo alaye rẹ o ni on ri i pe agbaregbabo gbogbo rẹ, Dokita Azikiwe jebi iwa madaru lori gbogbo ọran na.

Alaga Igbimọ Iwadi na Ọlọla Stafford Foster-Sutton Olori Onidajọ Agba Apapọ Ijọba Naijiria si dupe lọwọ gbogbo awọn ala-basiẹpọ rẹ, gbogb eleri ati gbogbo awọn ti o lọ ikoko wọn fun iferan ọran iwadi na.



Ọgbẹni H. J. M. Mackenna

* * *

O si pari ipade ijoko iwadi na ni ọjọ Eti ti ise ọjọ kẹrindinlogun osu yi, o ni ti on ba pari eto ayọrisi rẹ tan on o fi sọwọ si Ọlọla Alan Lennox-Boyd Asoju Ijọba Gẹesi ni Londonu ti o gbe ise iwadi na le on lọwọ. Iti irohin ayọrisi na ba ti jade ni a o ti te e jade fun gbogbo nyin gbọ.

## Ẹgbẹ Afẹnifẹre bori Ẹgbẹ N. P. C.

Lati oju ewe kini

Josiah Sunday Olawoyin ti ise akowe agba Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ni Ọffa ati agbegbe rẹ ti awọn Ẹgbẹ Olose fun ni asoju ni o gbori ninu idibo na.

Ọgbẹni Olawoyin ti ise asoju Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni o ṣẹgun Ọgbẹni Ezekiel Folayan asoju ti Ẹgbẹ NPC yan sode lati dibo fun. Ibo ti Ọgbẹni Olawoyin (A.G.) gba je 2,588, ibo ti Ọgbẹni Folayan (NPC) gba je 1,758.

MALLAM AMINU KANO KUNA

Ninu ibo ti o tona-taara ti nwọn di ni Iha Ila-Orun ilu Kano, Mallam Aminu Kano ti ise olori Ẹgbẹ Northern Elements Progressive Union (NEPU) kuna ninu ibo na patapata; ibo ti o gba je 1,776 pere. Eyiti abanidije rẹ, Alhaji Dantata ti awọn Ẹgbẹ NPC yan sode lati dibo fun; ibo ti o gba ti o fi ṣẹgun Aminu Kano je 2,019.

Nwọn koi ti pari idibo Igbimọ Ipinle Ariwa na tan titi a fi nko irohin yi. Bi nwọn ba ti pari re si, e o ma a gbọ o.


AWON OGBOLOGBO

(SCRAP)

OJE (LEAD)

IDẸ (BRASS)

BABA (COPPER)

AWỌN ALOKU IRIN
ERỌ MOTO (RADIATORS)

PAANU AYỌ (ALLUMINIUM)

JE OWO

Ko wọn wa ta fun

BUCK (NIGERIA) LTD..

2. AERODROME ROAD, APAPA.
TELEPHONE
55177.

MERCEDES-BENZ



THE 5/6 TON LORRY FOR

★ RELIABILITY AND LONG LIFE
★ LOW FUEL CONSUMPTION
★ HIGH PERFORMANCE

WITH A FULLY ORGANISED "AFTER SALES" SERVICE
AT MODERATE CHARGES
SUPERVISED BY EXPERT ENGINEERS FROM THE
MERCEDES WORKSHOPS.

LEVENTIS MOTORS

DISTRIBUTORS FOR NIGERIA


Printed and Published by the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd., 5/7, Apongbon Street, Lagos

# Ọmọ Erin'le ẹ fi eyi si ero

### Lati Ọwọ NATHANIEL ỌLAOYE, Akim-Oda G.C.

MO pe akiyesi ẹnyin ọmọ Erinle ti o wa ni ile ati ni idalẹ si alaye pataki ati si ajọmulo eyiti o ba je imọran nitori rẹ fun ire ilu wa. Yoruba ni "pipe ni a pe e gbọn a ki i pe go" awọn babalawo si i tun ma a ki ifa kan pe: "Ika wo o, Iwori wo o ohun a ba jọ wo ngun ni ngun".

Mo ṣakiyesi pe a ti mba a bọ pe, ti a ti wa labẹ Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni Ilorin gẹgẹbi a ti ba ni owọ awọn baba wa ni awa si tele ipasẹ rere wọn na, nipa pe ki a maṣe tẹ ofin Ijọba. Leti ki a si ma a jọsin iṣẹ wa fun Ijọba nipa sisan owo-ori wa deede.

Mo si wa ṣe akiyesi pe bi a ti mbu ola fun Ijọba to, o dabi ẹnipe awọn Olotu Ijọba na ko ka wa kun to be, nitori ninu ohun mẹ... ti nṣe ọrandun wa ni ilu wa ti a bere fun (1) Post Office (2) Kotu Ibilẹ (3) pe ki nwọn ṣa wa tun titi arin ilu ṣe ki nwọn si ba wa yọ ọda si i nitoripe agbara ojo ti ba gbogbo titi arin ilu na jẹ ati (4) pe ki Ijọba fi kun owo ọba wa, nitori owo ti o ngba ti kere pupọju, ko si ọkan ninu nkan wọnyi ti Ijọba ṣe fun wa.

Nigbati awọn kan ba dide nwọn a ma a so pe Ijọba wa fẹran wa pupo, mo ka iru ọrọ be si ọrọ ... ọkan iru ifẹran wo ni ki a ma a da owo ori ti Ilọrin npe ni owo-ọpa lọdọ... ki a ma ri nkan-kan pataki dimu pe ohun ti Ijọba ṣe ni pataki fun idagbasoke ilu wa niyi. Bi a ko tilẹ bere fun nkan wọnyi, ẹtọ Ijọba ni ki o ṣe e fun wa, a si tun mbere, a o dakẹ lẹnu aibẹ ...abo ni, nwọn ko dahun.

Mo fẹ ki gbogbo ẹnyin ọmọ Erinle ti e ba mọ ise ki ẹ lo o fun ogo ilu nyin, ki ise fun anfani ara ẹni nikan ni a ṣe ni ilaju ati ẹkọ, fun anfani ẹbi ẹni, ore ẹni ati ilu ẹni ni.

Asiko idibo ni o si bere ni Ipinlẹ Ariwa yi, ki ẹ ro dada ẹniti o ba to ti a si yẹ ni ki ẹ dibo fun un, ẹniti ẹ ba mọ pe ifẹ ilu wa wa ni ọkan re, ti ko ni i je ti ara rẹ nikan ni yio mu gbọ lẹhin bi awọn ti a ti yan sibẹ lati agbegbe Ilorin ti ṣe koja.

Gbogbo ilu ti o je ti Yoruba ni Ipinlẹ Ariwa ni a ngbọ gbogbo bi nwọn ti nfẹ ilu wọn si ninu iwe "Irohin Yoruba" pe bi awọn Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti nṣe fun gbogbo awọn ilu abẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun gbogbo ni awọn nfẹ fun ilu awọn. Nitorina ẹ jẹki a pa ẹnu pọ bere ohun ti o tọ fun ilu wa. Ọmọ Erinle ni emi, ire ilu mi ni emi yio si ma a wa, bẹna ni ki gbogbo ẹnyin yoku o pinnu ki a si ma a gbọ ohun nyin ninu iwe "Irohin Yoruba" nigbagbogbo.

Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gba mi, oju ko feraku o.

# Azikiwe ni, Banki on ko le parẹ ni oju ẹmi on

NI ọjọ Iti ti iṣe ọjọ keje oṣu yi, nigbati Dọkita Azikiwe, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun mba ọrọ eri re lọ niwaju Igbimọ Iwadi "African Continental Bank" ni Ọgbẹni Shawcross ti iṣe Agbẹjọro Ọgbẹni Eyo so pe bi o ba ṣe pe nwọn ti dawo iṣe Banki na duro ni, ṣe be ni gbogbo awọn ti o ti sanwo ipin tiwọn nibẹ yio parẹ si. Ati ti Azikiwe alara paapa ati ti awọn ẹbi rẹ ati ti Ọgbẹni Ojukwu ti ẹnikookan san sile kookan pere fun ipin kookan yio padanu owo wọn ni.

Nigbati Dọkita Azikiwe gbọ eyi ni o ba binu "tatọ soke f'oju gba a" pe on ko ni la oju on ... loju ẹmi on ki Banki on yi ṣe oju on parẹ. O dahun pe awọn ti o ni owo ninu Banki na ko padanu owo wọn, ṣugbọn o gba pe nibiti sile kookan ninu ponun kookan ni awọn ẹbi on ati awọn iṣe onipowo san lati le je gaba lori ẹgọrin ipin Banki na ti a ba da a si ọna ọgọrun (80%).

O si tun so siwaju pe on ati awọn ẹbi on kanna yi ni awọn tere owo jọ f'oturn l'odi ti awọn fi da ... na silẹ. Dọkita Azikiwe ti pari ẹri tirẹ ṣugbọn wọn ko iti pari ọran iwadi na.

## LAWSON NI KI ỌLỌPA MA MU AWỌN ONIKIRI ỌJA MỌ

EKO.

NINU ipade ti Munisiba Eko ṣe ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kefa oṣu yi ni Alaga Igbimọ na Ọgbẹni A. O. Lawson ti so pe awọn ọlọpa Munisiba Eko ko ni ẹtọ gẹgẹbi akoṣilẹ ofin lati ma a mu awọn ti nkiri-ọja kakiri igboro Eko.

Alaga na ni ofin ti o ni ki enia maṣe kiri ọja kakiri igboro ko ba awọn agbalagba wi, ofin fun awọn ọmọde ti koi ti balaga ni, ko si ẹtọ fun awọn ọlọpa Munisiba ... ma a ko awọn ti nkiri ọja.

Awọn ọl... Ijọba ti o ni ẹtọ ati mu awọn ọmọ wẹwẹ ti o nkiri ọja ko ni ẹtọ lati mu ọmọkunrin ti o ba ti dagba kọja ọdun mẹrinla ati ọmọbinrin ti o ba ti kọja mẹrindinlogun.

Alaga na ni ki nwọn ti kilọ fun awọn ọlọpa Munisiba Eko na ti nwọn nmu irufẹ awọn ọlọja na pẹlu, nitori eleyi ki ṣe iṣẹ ti Ijọba gba wọn fun.




# OPEL KAPITAN

YARA, O LAGARA, O SI ṢE GBẸKẸLE



£898 ex Lagos

OPEL KAPITAN NA—Mọto nla arinrin-ajo kan ti o nda ṣiṣẹ, owo pọku ni i. Enjinni oni 2.5 litre ni ẹrọ ti o fun un ni agbara ti nwọn fi nwa a pẹlu irọrun. Nwọn ti mọ ọ kakiri agbaiye pe o ṣe gbẹkẹle ati pe alopẹ re je iyanu. Tentiim rọba ti o wa ninu rẹ nfun ẹniti o nwa a ati ero inu re ni ọpọlọpọ igbadun.

O yara, o ni lagbara; ko ga, o mọ ni iwọn iba, o si din inawo ku; o ni igbẹkẹle, o ni alopẹ—ngbogbo nkan wọnyi ni o mu ki OPEL KAPITAN je ọkan ninu awọn mọto ti nwọn nfẹ ma a ri l'oju titi l'ode l'oni! Ko ẹkọ nlanla lara awọn anfani ti o wa lara mọto yi nipa ero iṣe rẹ ati igbadun rẹ.

UTC MOTOR DEPARTMENT

LAGOS · APAPA · IBADAN · ENUGU · KADUNA · JOS · KANO



IPARA TO DARA JULỌ






MENTHOLATUM

... THE MENTHOLATUM CO. LTD. ... Slough, England.

# IRIN - AJO OLOYE S. L. AKINTỌLA NI IPINLẸ ARIWA



















